# AWỌN ỌMỌ HEBERU MẸTA
## Daniẹli 3:1-30
## ẸKỌ 420 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Kò tọ si wa lati fi èsi kan fun ọ nitori ọ̀ran yi. Bi o ba ri bẹ̃, Ọlọrun wa ti awa nsìn, le gbà wa lọwọ iná ìleru na ti njo, on o si gbà wa lọwọ rẹ, ọba. Ṣugbọn bi bẹ̃kọ, ki o ye ọ, ọba pe, awa ki yio sìn oriṣa rẹ, bẹ̃li awa ki yio si tẹriba fun ere wura ti iwọ gbé kalẹ" (Daniẹli 3:16-18).**

**I Iyasi-mimọ Ere Wura Ọba**

1 A gbé ère ti giga rẹ̀ jẹ́ aadọrun-un ẹsẹ ti ibu rẹ̀ si jẹ́ ẹsẹ mẹsan-an kalẹ lẹba Babiloni, Daniẹli 3:1; 2:31, 32; Orin Dafidi 115:4-8; Isaiah 2:20; Ifihan 9:20

2 A pe awọn onisẹ ti o wà ni gbogbo igberiko si ibi iyasi-mimọ naa, Daniẹli 3:2, 3

3 A paṣẹ fun gbogbo eniyan pe bi wọn bá ti gbọ́ iro orin pe ki wọn ki o foribalẹ fun ère naa, Daniẹli 3:4-7

**II A Gbé Ṣadraki, Meṣaki ati Abẹdnego sinu Iná Ileru**

1 A sun awọn ọmọ Heberu mẹta naa ni ẹsùn pe wọn ṣe afojudi si aṣẹ ọba ati awọn oriṣa rẹ̀, Daniẹli 3:8-12

2 Wọn kọ̀ lati tẹriba fun aṣẹ ọba ti o n pa leralera, Daniẹli 3:13-18; Matteu 10:18, 19, 28; Jobu 13:15

3 Ọba paṣẹ ninu ìrunu rẹ̀ pe, ki a gbé wọn jù sinu iná ileru, Daniẹli 3:19, 20; Orin Dafidi 76:10; 50:15

4 A gbé awọn ọmọ Heberu mẹta naa sinu ina ileru, ooru iná si pa awọn ti o gbé wọn lọ, Daniẹli 3:21-23; Orin Dafidi 23:3, 4; 2 Timoteu 4:17, 18

**III Idande Iyanu ati Iwariri Ọba**

1 "Awọn ọkunrin mẹta kọ a gbé sọ si ãrin iná ni didè?" Daniẹli 3:24

2 "Wò o, mo ri ọkunrin mẹrin … irisi ẹni-kẹrin si dabi ti Ọmọ Ọlọrun" Daniẹli 3:25

1 Wọ́n jade wá siwaju gbogbo eniyan, òórùn iná kò tilẹ kọja lara wọn, Daniẹli 3:26, 27; Heberu 11:34; Isaiah 43:2; Orin Dafidi 34:7

2 Nebukadnessari fi ọla ati ogo fun Ọlọrun Israẹli, Daniẹli 3:28, 29

3 A gbé awọn oloootọ iranṣẹ Ọlọrun ga, Daniẹli 3:30

ALAYE

**Ère Wura**

O ṣe e ṣe ki ero Nebukadnessari lati yá ère giga kan wá lati inu àlá ti o lá ni ọdun diẹ sẹyin nigba ti o ri ère eniyan kan ti o duro lori ọwọ̀n giga kan. Ohun iranti iyebiye ti o ga ni aadọrun ẹsẹ (90 ft) yii ni o fẹ́ yà si mimọ́ fun ọla nla rẹ̀. Nigba ti Daniẹli n tumọ ala fun un o ti wi bayii pe, "Iwọ li ori wura yi." Daniẹli si tun ti rán an leti pe Ọlọrun Ọrun ti fun un ni ijọba alagbara yii. Ọba onigberaga yii kò fiyesi ọ̀rọ wọnyii, bi ko ṣe bẹẹ oun i bá ti bẹru lati gbé ara rẹ̀ ga. Bayii ni Nebukadnessari ti o n ṣogo ninu agbára ti a fi fun un, dabi apẹẹrẹ aṣodisi-kristi ti yoo mu ki awọn eniyan yá ère fun ọla oun (Ifihan 13:14). Ni nnkan bi ọdun diẹ sẹyin ọ̀kan ninu awọn afi-agbara-ṣakoso ni ilẹ awọn eniyan funfun gbé ère kan kalẹ fun ara rẹ̀ ni ilẹ Romu, ère naa ga ni ọtalenigba ẹsẹ o din mẹwaa (250 ft).

**Ikilọ**

A ka ninu Ẹksodu 20:23 pe: "Ẹnyin kò gbọdọ ṣe ọlọrun fadaka, tabi ọlọrun wurà, fun ara nyin." Jeroboamu ọmọ Nebati mú Israẹli dẹṣẹ nipa gbigbe ẹgbọrọ maluu wura meji kalẹ, ọ̀kan ni Beteli ati ekeji ni Dani (Wo 1 Awọn Ọba 12:29).

**Awọn Onişẹ Pejọ**

Ipejọpọ awọn ọmọ-alade, awọn baalẹ, awọn balogun, awọn onidajọ, awọn oluşọ işura, awọn igbimọ ati awọn ijoye, fẹ fi tifẹtifẹ wolẹ lati sin ọba. Lode oni, a ri ọpọ ohun ti ayé n fi ẹtọ oşelu şe dipo lati duro loju ọna tootọ. A yan Şadraki, Meşaki ati Abẹdnego ni olori awọn igberiko Babeli (Daniẹli 2:49). Awọn pẹlu wa lara awọn ti o pejọ pọ ni pẹtẹlẹ Dura. Aşẹ kan naa fun awọn ti o wà nibẹ ni a pa fun wọn. Nigba ti ohun elo orin ilẹ Kaldea bẹrẹsi kọrin, Ọlọrun gbé ọpagun kan dide ninu ọkàn wọn gẹgẹ bi O ti sọ ọ lati ẹnu Isaiah ni ori kọkandinlọgọta (59) ẹsẹ kọkandinlogun (19) ni nnkan bi ọgọrun ọdun şaaju akoko yii pe: "Nigbati ọta yio de bi kikún omi, Ẹmi OLUWA yio gbe ọpágun soke si i." Ọpọ ni a ti fi afẹfẹ-yẹyẹ ati orin igbalode ti ode oni gbá lọ. Ogunlọgọ ti kò ni ipinnu ara wọn ni a ti fi imọran ọ̀wọ́-ero gbá lọ; şugbọn Ọlọrun ni işẹ́ ti o jinlẹ ju igbagbọ́ ori lọ fun ọkàn ọmọ-eniyan. "Ibi titun" ni o n mú igbagbọ́ yii wá sinu ọkàn pe, "Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa?" (Romu 8:31).

Lai fi ipo òye ti a fi wọ́n si pè ati lai bẹru ipá ati agbára ati ohun ti ọba yii le fi wọn şe, awọn ọmọ Heberu mẹta wọnyii kọ̀ jalẹ lati ba ipinnu wọn jẹ́, wọn si jẹ́ oloootọ si Ọlọrun ninu iduro wọn. Nigbooşe Jesu paapaa sọ pato iduro wa lori awọn ọran bawọnni nigba ti o wi bayii pe, "Njẹ ẹ fi ohun ti işe ti Kesari fun Kesari, ati ohun ti işe ti Ọlọrun fun Ọlọrun" (Matteu 22:21). Ti ọba ni awọn nnkan ti i şe ti ilu, awọn ti i şe ti isin si jẹ́ ti Ọlọrun.

**Kò si Ọlọrun Miiran**

Aşẹ ọba rú ekinni ninu Ofin Mẹwaa. Kò si orilẹ-ède miiran afi awọn Ju ti o le wi pe aşẹ ọba yii nira, nitori kò di awọn keferi lọwọ lati sin awọn orişa wọn. Nitori awọn Ju ni a fi gbé aşẹ yii kalẹ lati ọwọ́ awọn wọnni ti o n şe ilara ipo giga ti a fi wọn si ni aafin ọba. Nitori naa wọn rọ ọba lati paşẹ nipa awọn ti kò tẹriba fun ilana, pe kikọ̀ ti wọn kọ̀ lati juba ki i şe ohun miiran bi ko şe işọtẹ si Nebukadnessari, ti i şe "ori" ni gbogbo ijọba nipa ọran ẹsìn. Ẹ̀sun pe "Nwọn kò sin orişa rẹ, wọn kò si tẹriba fun ere wura ti iwọ gbé kalẹ" şe iranlọwọ lati rú ibinu ọba soke ju bẹẹ lọ.

**Ẹri fun Ọlọrun Otitọ**

Esi ti awọn ọdọmọkunrin mẹta naa fi si ibeere ọba jẹ́ apẹẹrẹ igbẹkẹle giga ninu Ọlọrun lai si ibẹru. Wọn fẹ ki ọba mọ̀ pe wọn ki yoo fi ọwọ pa ẹsẹ lori tabi ki wọn yẹ iduro wọn lori ọràn ti o rán orilẹ-ède wọn lọ si igbekun – ani ibọrişa. Ọlọrun fi àye silẹ pe ki a mú wọn wá siwaju ọba ki a baa le gbọ́ ẹ̀ri wọn, ati pe ki ẹ̀ri fun Ọlọrun otitọ ki o le di mimọ̀ ni gbogbo ayé.

**Ọba Kẹgan**

Nigba ti Nebukadnessari beere ibeere yi pe "Ta li Ọlọrun na ti yio si gba nyin kuro li ọwọ mi?", ó dé eti-igbọ́ Ọlọrun bi ọ̀rọ ẹ̀gan Sennakeribu nigba ti Isaiah sọ fun awọn iranşẹ ọba Assiria pe Ọlọrun yoo gba Israẹli kuro lọwọ Assiria. Sennakeribu fọnnu bayii pe, "Tani ninu gbogbo awọn orişa ilẹ wọnni ti o gbà ilẹ wọn kuro lọwọ mi, ti OLUWA yio fi gbà Jerusalẹmu kuro lọwọ mi?" (2 Awọn Ọba 18:35). Farao sọ iru ọrọ igberaga bẹẹ: "Tali OLUWA, ti emi o fi gbà ohùn rẹ̀ gbọ́ lati jẹki Israẹli ki o lọ?" (Ẹksodu 5:2). Ọlọrun ti sọ fun wa Ẹni ti Oun i şe. O wi pe: "Emi li OLUWA: eyi ni orukọ mi: ogo mi li emi ki yio fi fun ẹlòmiran, bẹ̃ni emi ki yio fi iyin mi fun ere gbigbẹ́" (Isaiah 42:8). O tun wi pẹlu pe: "Ọlọrun li onidajọ: o sọ ọkan kalẹ, o gbé ẹlomiran leke" (Orin Dafidi 75:7); ati pe "Kò si aşẹ kan, bikoşe lati ọdọ Ọlọrun wá: awọn alaşẹ ti o si wà, lati ọdọ Ọlọrun li a ti làna rẹ̀ wá" (Romu 13:1). Nitori naa, ta ni eniyan ti oun yoo fi maa gberaga si Ọlọrun Olodumare?

**Irunu Kikoro**

Ibinu ọba kò ni iwọn nigba ti awọn ọmọ Heberu wọnyii dojukọ ọ, ni iduro gangan pẹlu igboya ninu agbara Ọlọrun Israẹli. Aşẹ si jade pe ki wọn ki o dá iná ileru naa ki ooru rẹ̀ gbona ni ilọpo meje ju bi a ti i mu un gbona ri lọ. Pẹlu agbada, şokoto, ati ibori wọn, ati awọn ẹwu wọn miiran, a gbé wọn sọ ni didè sinu iná ileru naa. Bi ooru ina naa ti pọ̀ to, o pa awọn alagbara ninu ogun, awọn ti eniyan le bẹru jù lọ. Awọn onde naa şubu lulẹ ni didè si aarin iná ileru naa. Njẹ kò yẹ ki awọn ọdọmọdekunrin wọnyii yẹ iduro wọn wò iru eyi ti yoo mu ki wọn sọ ẹmi wọn nù nitori ijolootọ wọn nigba ti iwọnba ohun ti ofin n beere lọwọ wọn ni pe ki wọn fi ori balẹ fun ère, şugbọn kò si igbọjẹgẹ ninu awọn ọdọmọdekunrin

wọnyii. Wọn kò daba ati dibọn nipa fifi ara mọ aṣẹ ọba. Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe: "Ẹ mã takéte si ohun gbogbo ti o jọ ibi" (1 Tẹssalonika 5:22).

Nigba ti igbagbọ́ wa ba wà labẹ idanwo ati iyiiriwo kikoro, o dara lati ranti Paulu Apọsteli: "Awa si mọ̀ pe ohun gbogbo li o nṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun, ani fun awọn ẹniti a pè gẹgẹ bi ipinnu rẹ̀" (Romu 8:28). Kikùn tabi ṣiṣe aroye nipa ipin wa a maa ṣe iranwọ fun ọta ẹmi wa. A fi ye ni pe ohun ti o n ṣẹlẹ si wa kò ṣe pataki to bẹẹ bi iru iha ti a n kọ si i. A le lo o gẹgẹ bi atẹ̀gùn si àye giga ninu Ọlọrun, o si le di okuta idigbolu ti o le mú wa ṣubu bi a bá mú oju wa kuro lara Balogun Igbala wa.

**Ilaja Ọlọrun**

Nigba ti ọba wo ina ileru naa, dipo ti i ba fi ri opin awọn aṣelodi naa, o ri ẹni mẹrin dipo ẹni mẹta; ati irisi ẹni kẹrin si dabi ti Ọmọ Ọlọrun. Siwaju si i, aanu Ọlọrun otitọ hàn fun ọba onigberaga yii. Awọn ondè ti o wà ninu ina ileru naa ri i pe niṣe ni iná naa tú wọn silẹ kuro ninu idè wọn, wọn si dide, wọn si bẹrẹ si i rin. Awa pẹlu ni idanwo iná, eredi eyi ti a ṣe alaye rẹ̀ fun wa ninu 1 Peteru 1:7: "Ki idanwò igbagbọ́ nyin, ti o ni iye lori jù wura ti iṣegbe lọ, bi o tilẹ ṣepe iná li a fi ndán a wò, ki a le ri i fun iyin, ati ọlá ati ninu ogo ni igba ifarahàn Jesu Kristi." Bi a ba ti n jọwọ ara wa fun Ọlọrun tó ninu idanwo wa, bẹẹ gẹgẹ ni awa yoo bọ́ lọwọ aniyan ayé yii tó, ti a o si ni ominira pọ̀ tó ninu Kristi (Luku 21:34-36).

**Diduro De Akoko Ọlọrun**

Wọn kò daba ati jade kuro ninu ina naa, ṣugbọn wọn duro de aṣẹ ọba ti o wi pe, jade wa; gẹgẹ bi Noa pẹlu ti duro ninu ọkọ̀ lẹyin Ikun Omi titi di igba ti Ọlọrun fi wi fun un pe ki o jade (Gẹnẹsisi 8:12-18). Ijẹri ọba pe iranṣẹ Ọlọrun Ọga-Ogo ni wọn, ti sọ oriṣa-koriṣa di ọlọrun yẹpẹrẹ. O pari ọ̀rọ rẹ̀ bayii pe: "Kò si Ọlorun miran ti o le gbà ni là bi iru eyi." Dajudaju Ọlọrun fi ipa Rẹ̀ hàn lati yọ awọn olododo nitori ko tilẹ si òórùn iná lara aṣọ wọn, bẹẹ ni irun ori wọn kò jona, aṣọ wọn kò si yipada. Fi eyi wé iparun awọn akọni jù lọ ninu ogun ọba. Ọlọrun Ọrun yí ofin ọba pada! A n pa a lowe pe: "Riro ni ti eniyan ṣiṣe ni ti Ọlọrun." Ijolootọ wọn si Ọlọrun mú igbega wá lati ọdọ ọba ayé ati ẹrin musẹ lati ọdọ Ọba Ọrun.

AWỌN IBEERE

1 Iru ipo wo ni alá Nebukadnesari fi i si?
2 Ṣe apejuwe bi o ṣe di ẹni ti o ni imọ Ọlọrun otitọ.
3 Ofin kelo ni o wà ninu ọkàn awọn ọmọ Heberu yii, ti wọn fi kọ̀ lati foribalẹ fun ère?
4 Ileri wo ninu Iwe Wolii Isaiah ni a fi silẹ fun iranwọ awọn ti o ba wà ninu ipo bayii?
5 Ta ni wá bẹ awọn ọmọ Heberu naa wò ninu iná ileru?
6 Ṣe alaye ohun ti iná naa ṣe.
7 Njẹ o ni ère fun awọn ọmọ Heberu naa lati jẹ́ oloootọ si Ọlọrun? Lọna wo?
8 Ki ni ṣe ti Ọlọrun kò fi gbà wọn ki O má si jẹ ki a gbé wọn sọ sinu iná ileru naa?
9 Ki ni iyipada nla ti iṣẹ-iyanu yii mú bá ayé igba nì?